Ọmọ mi, bi awọn ẹlẹṣẹ ba tan ọ, iwọ ma ṣe gba.
OWE 1 : 9

# Irohin Yoruba

VOL X No 466 — MONDAY JUNE 14, 1954 — KOBO KAN (1d)



E ma a polowo oja nyin sinu iwe Irohin Yoruba


# Oba Oyinbo F'Oye K.B.E. Da Oba Alake L'ola.

**NI ojo Ojobo ti ise ojo kewa osu yi ni Alaiyeluwa Elizabeth Keji Oba-birin Ilu Oyinbo se ajoyo ajodun Ojobi re, fun iranti Ajoyo Ajodun na o fi oye "Ogagun Nla kan ninu Ijoba Geesi" ( Honorary Knight Commander of the Most Excellent Order of the British Empire ) da Oba Alaiyeluwa "Ololа Oladapo" Ademola Keji Alake Abeokuta l'ola.**

Ọba Alaiyeluwa Ademọla Keji Alake Abẹokuta jẹ ọkan ninu awọn Ọba olokiki ati Enu-ọwọ ni ilu Ijọba Iwọ-orun Nigeria, o ti dagba to ẹni ọdun mọkanlelogorin nisisiyi, o si ti wa lori oye Ọba Alake fun ọdun mẹrinlelọgbọn (lati ọdun 1920).

O ti wa ninu Ajọ Igbimọ Aṣofin Nigeria atijọ lati ọdun 1946 di 1951, ati nisisiyi o si tun jẹ ọkan ninu awọn Aṣoju Ijọba Iwọ-orun ninu Apapọ Ajọ Igbimọ-Nla Aṣofin Nigeria (Member of the House of Representatives.) Tẹlẹtẹlẹ awọn Ọba ilu Oyinbo ti o ti nje ṣiwaju Alaiyeluwa Elizabeth keji Ọba-birin ilu Oyinbo yi ti fi oye C. B. E. ati C. M. G. da Ọba Ademọla keji Alake Abẹokuta na l'ọla ki Ọba-birin yi to wa fi oye "K. B. E." yi ti o ga ju gbogbo ti atẹhinwa lọ da a l'ọla yi.

Ade a pẹ l'ori, Bata a pẹ l'ẹsẹ, a gb'ori oye j'oye Ademọla Keji Alake Abẹokuta. Kabiyesi!

Ninu awọn ogunlọgọ enia ti Ọba-birin Ilu Oyinbo na tun fi oye ọjọbi rẹ ti 1954 yi da l'ọla ni Ogbẹni Ernest Ikoli, Alagba ninu awọn onkwe Irohin Nigeria, on ni Ọba-birin na tun fi oye "Honorary Officer of the Most Excellent Order of the British Empire" (O.B.E) da l'ọla. Oye um'ori o.



Ọba Alaiyeluwa Oladapọ Ademọla, K.B.E.

## Adegbemi Be Olotu Wo

EKO-Ni ọjọ Eti ti iṣe kọkanlelogun oṣu karun ọdun yi ni Ọgbẹni Alimi Adegbemi, onibara Iwe Irohin Yoruba ni Kadjebi-Buem, Gold Coast, kuro ni ilu na, o si de si ilu rẹ ni Ede ni ọjọ ketadinlọgbọn oṣu na fun ibẹwọ awọn enia rẹ lati ti ara mọ wọn fun igba diẹ ati lati tun ṣe gbogbo eto ti o ṣeku fun ile rẹ ti o ti kọ silẹ.

Inu Alagba Ọgbẹni Emanuel ti iṣe baba rẹ ati Oloye Aswaju, Adajọ Kotu Ibile Ede ti iṣe ẹgbọn rẹ dun pupọ lati gba a ni alejo. Nigbati o di ọgbọnjọ oṣu na ni o wa si Eko, o si wa ṣe ibẹwo Olotu Irohin Yoruba ni ọjọ keji, inu Olotu pupọ dun lati gba a ni alejo.

Lẹhin ti nwọn jijọ ṣe eto lori bi gbogbo nkan ti nlọ si nihin ati l'ọhun tan ni Olotu ba mu u yika gbogbo ile-iṣẹ itẹwe wọn, inu alejo na si dun si gbogbo awọn nkan ti nwọn fi han an ati alaye lori ilo awọn ero irinṣẹ itẹwe ra. O si dupẹ pupọ lọwọ Olotu ki o to ma a lọ.



Ọgbẹni Alimi Adegbemi Akọwe Ẹgbẹ Ọmọ Ibile Ede Oke-Okun

Ni ọjọ keji ni o tun pada si Ede lati lọ pari awọn iṣẹ ile rẹ ti o ku. Nigbati o di ọjọ kejọ oṣu yi ni o tun pada si enu iṣẹ owo rẹ ni Oke-Okun (Kadjebi-Buem, Gold Coast) a lọ a dẹra abọ-asunwọn o, od dẹrẹ ki i ku s'oko iwaju.

## *Gada Baje, Moto Ja S'odo, Enia Marun Ku*

OYO-Ni aipẹ yi ni mọto akero kan ja lu odo nigbati o gun ori gada Origbemidele, ni gada bu ya lulẹ eyi ni o mu ki mọto akero na fi ṣubu sinu odo na, ti awọn enia marun fi ku, ọpọlọpọ ero inu mọto na ti ko ku ni nwọn si fi ara pa.

Eyiti o ṣe enia ni anu ju ni ti obirin kan Nimọta Ajikẹ ti o mbọ lati abule Legba, ni busọ mẹdogun si Ọyọ lati wa ṣe oku baba rẹ ni Ọyọ, o si mu ọmọ rẹ ọkunrin ọmọ-ọlọdun-mọkanla dani, on pẹlu ọmọ rẹ na wa ninu awọn marun ti nwọn ku sinu ijamba mọto na.

Olorun ma jẹki a rin ni ọjọ ti ebi npa ọna, ọjọ buruku eṣu gb'omi mu lọwọ ijamba mọto ati iku ojiji, Oluwa rere gba wa.


PR-GRESS

O! ARE U MISSING

16 hours of it for less than

3D A DAY---GET REDIFF-SION


## *Odun Itunu-Awe Dun Pupo L'Eko*

**EKO- Ni ojo Ojobo ti ojo ise keta osu yi ni awon Imale se Odun Ikirun-awe, Odun na si dun o larinrin, nigbati ojo odun na ti ku ola ni nwon ti bere aisun odun ti ilu orisirisi ndun yi gbogbo ilu ka ti nwon njo ti nwon nyo titi ile fi mo.**

Nigbati ilẹ mọ, lati agogo meje owurọ ọjọ na ni gbogbo wọn Feku inu l'obirin ti bẹrẹ si wọ orisirisi aṣọ olowo-iyebiye ni ọkan-ko-jọ-ọkan, ti nwọn si da ni orisirisi aṣa aṣọ wiwọ ilẹ wa, niti aṣa oyinbo ati ni aṣa awọn Arabu ti gbogbo wọn si dorikọ ehin-odi ni Obalende-Ikoyi nibiti nwọn gbe nkirun ọdun Iọdọdun.

Ọba Eko, Adele Keji ati awọn Ijoye rẹ ati awọn Musulumi pataki pataki ni o ṣe aṣaju wọn lọ si Idi ọdun na. Lemọmu Ilu (Mọṣalaṣi Jumọ), Abudu Karimu Nolla ni o kirun fun awọn ijọ Ọba Adele.

Ni apakan ibiti awọn ijọ Ọba na gbe kirun ni, awọn ijọ Ahmadiyya eyi,


Wo oju ewe kerin




Alaiyeluwa Adele Keji Ọba Eko ni o wa ni arin awọn Oloye rẹ nigba ti nwọn gbe nkirun ọdun Itunu Awẹ ni Idi.

